## "SERVICE PRESS LTD" JARE NNAMDI AZIKIWE


# IROHIN YORUBA

Ẹẹ̀ Oro Wa— "IWAJU L'OPA EBITI NRE SI"


### Akiyesi

A fẹ ki awọn onibara wa ma san owo si apo wa dede, enit ko ba san owo tirẹ, ki o ma yẹ a lẹnu bi a ba da a duro lojiji, a o si gba owo wa lọwọ rẹ

OLOTU
IROHIN YORUBA

## BANKI TITUN NI OWODE : LOYA LADIPO MOORE D'OLOYE BAGBIMO IJEMO


VOL. IV NO 694 IBADAN, MONDAY, DECEMBER 3 1951, OWO IWE IROHIN YORUBA — KOBO KAN (1d)


## "Service Press" Jare Azikiwe

Ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Kotu Alagba-mẹta (West African Court of Appeal) da Service Press Ltd. lare lori ẹran ẹjọ ti Dọkita Nnamdi Azikiwe pe e pe o ba on ni oruko jẹ. Nwọn si so pe ki Azikiwe lọ san pọnun mẹtadinlogun sile mẹdogun ati kobọ meji (£17-15-2) fun Service Press Ltd, fun gbogbo wahala ati inawo rẹ lori ẹjọ na.

Obon ti Azikiwe pe ẹjọ fun ni pe Service Press Ltd. ba oruko on jẹ nipa irohin kan ti o lẹ jade ni 9/12/48 pe on ngbero a ti ku owo Ẹgbẹ N. C. N. C, mọlẹ ati pe on o gba ẹgbẹrun pọnun (£1000) lọwọ "Service Press" fun ìborukọ-jẹ. Niwaju Adajọ agba Ologbe S B Rhodes ni awọn kọkọ ro ẹjọ na, Ologbe Adajọ na si da "Service Press" lẹbi pe ki o lọ san ẹdẹgbẹta pọnun (£500) fun Azikiwe.

"Service Press" ko faramọ idajọ yi ni o ba fi gbe ẹjọ na lọ si Kotu Alaga-mẹta (West African Court of Appeal) lọdọ awọn ogunna gbongbo ti ida rọ lẹnu igbin. Nibẹ ni awọn gbe pari ọran ẹjọ na gẹgẹ bi a ti sọ soke yi. Lọya Rotimi Williams ni agbẹjọro Service Press ni idi ọran na. Lọya J. I. C. Taylor ni agbẹjọro ti Azikiwe.

### ENIA MERIN D'ELEWON FUN IDIBO-ERU

Ni ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu ti o koja yi ni awọn fi ẹjọ Jimọh Bello, Jimọh Afinyẹ, Wilfred Igweagu ati Eugene Aro sun Ijọba pe awọn lọ jẹ oruko olorukọ lati fi di ibo ni awọn ibi ti awọn gbe ndi ibo eyi ti o koja yi fun awọn aṣoju Eko ni Igbimọ Apero Nla ti Iwọ Orun Nigeria (Western House of Assembly).

Adajọ ti Glover Memorial Hall ri pe awọn jẹbi o si ju won si ẹwọn oṣu mẹta mẹta lati ṣiṣẹ aṣe kara. Nwọn fi ẹjọ Dizzy Daomola sun Ijọba pe o fi abuku kan Rufai Saibu ni Omididun Street "H" Ward" o si pe on ko jẹbi, awọn si fi ẹjọ rẹ si nọ.

Ẹ maa ka iwe
**Irohin Yoruba**
algbagbogbo fun oriṣiriṣi irohin



ỌBA ALAIYELUWA ADEDAMỌLA KEJI. Oṣilẹ Oke Ọna Abẹokuta nṣi Banki.

## Loya Ladipo Moore Di Oloye

Lọsulọlọ yi ni awọn fi Lọya Oladipo Moore jẹ Oye Bagbimọ Ijẹmọ Abẹ kuta. Awọn Oloye meji ti Ẹgba, Balekan ati Legun Ijẹmọ ni won wa lati Abẹokuta si Eko lati ṣe eto oye na. Lẹhin igba ti awọn jẹ oye na tan, Oloye Bagbimọ Ijẹmọ titun na fi jijẹ ati mimu tẹ awọn gbajumọ ati awọn ọlọla ore rẹ lọrun ni inu ile rẹ ti o wa ni Tinubu Street.

Baba Oloye titun yi, Ologbe Ọlọla Lọya Eric O. Moore ni ẹniti o ti jẹ oye Bagbimọ Ijẹmọ Abẹokuta na tẹlẹtẹlẹ ri. Lẹhin iku rẹ ni awọn Oloye Ijẹmọ ba ri pe ọmọ rẹ to aye na ropo ni awọn ba wa fi jẹ.

Awọn ẹniti o wa ni ibi ayẹyẹ na ni Dọkita F. A. Akerele, Ọgbẹni J. K. Randle, A. O. Dawodu B. A. Clair, Ọlọla Adeleke Adedoyin, Iya Afin Adebiyi (Lọya) ati Omidan Kofo Ademọla, B. A. (Oxon)

### IROHIN GUSAU

Ni nipẹ yi ni a da ẹka Ẹgbẹ Young Nawafe-Ud-Deen Society silẹ ni ilẹ yi (Gusau).

Awọn wọnyi ni oloye ati oṣiṣẹ ti awọn Ẹgbẹ na yan:—H A Akinyode, Alaga, S O Agboke, Igbakeji Alaga, Tiyamiyu Jimoh, Akọwe-Ẹgbẹ A A Aroguadade, Gbakeji Akọwe G A Akinfẹwa Akọwe owo, J T Asani, Gbakeji Akọwe owo, M Ade Ogunyẹmi Akapo owo Ẹgbẹ, R A Adam Alamojuto Iṣiro owo Ẹgbẹ

### E KU IDELE OLORI ẸGBE

ACCRA — Ninu oṣu kẹsan ọdun yi ni Ọgbẹni Y sufu Adeniji Alaga Ẹgbẹ Ọmọ Ogbomọṣọ ni gbogbo ilu Oke - kun (Gold Coast) lọ si ilẹ (Ogbomọṣọ) ọpọlọpọ enia ni o sin in wọ ọkọ pẹlu fabji. Alọ a dẹta abọ a sunọn.

## Banki Titun Ni Owode

OWODE ABẸOKUTA — Ni nipẹ yi ni awọn Olotu 'Pan-Nigerian Bank Limited' ṣi Ile-owo (Bank) kan si ilu yi. Ẹniti o ṣe iṣin ile ṣiṣi na ni Alufa S. A. Daramọla.

Awọn Ọba Alaiyeluwa Alimi Adedamọla Keji, Oṣilẹ Oke Ọna ati Ṣobẹkun Keji Agura Gbagura Abẹokuta ba awọn enia ti o wa nibẹ sọ ọpọlọpọ ọrọ iwuri ki awọn to bẹrẹ eto ṣiṣi Ile-owo na.

Ọba Oṣilẹ ni o kọkọ ṣi Ilẹkun kini, Ọba Agura ṣi ikeji, Ọgbẹni M Ọkanlawọn Balẹ Owode ṣi ikẹta, Sarki awọn Hausa ilu ibẹ ni ṣi ikẹrin. Lẹhinna ni awọn bẹrẹ si fi owo pamọ sibẹ, ti awọn akọwe si bẹrẹ si ṣe iṣẹ wọn.

Awọn Ọba Oṣilẹ ati Agura ni o kọkọ fi owo sibẹ, lẹhin na ni gbogbo enia si bẹrẹ si f'owo pamọ sibẹ. Diẹ ninu awọn ti o wa sibẹ ni awọn Oloye James, Balẹ Oke, G. F. D Gbadebọ Balogun Ilugun Ogunsọla, Apena Oke, Eman Fọlarin Balogun Ikereku, Yesufu Ṣolabi Sarumi Oke, Iyalafin Emilia Oṣimosu, Ọgbẹni J. S. Kotoyẹ ati ọpọlọpọ awọn Oloye ati Ọlọla ti ko si aye lati darukọ wọn.

## AKIYESI

Nipa ibere ati Iwadi lati ọdọ Awọn Ọmọ Awo Ologboni The White Brotherhood Lodge, Awọn Onibara wa, Ọrẹ ati Afẹnifunre enia, ki a ṣe alaye fun won bi Ẹgbẹ kan ti o pe oruko ara rẹ ni "THE ANCIENT KURAJEEH WHITE BROTHERHOOD LODGE" eyi ti o kede ara rẹ sinu Iwe Irohin Yoruba ti oṣu November, 26th 1951 ba faramọ, abi jẹ ọkanna pẹlu The White Brother-hood Lodge bi?



Inu wa dun pupọ lati ṣe alaye ati Idahun si ibere yi pe The White Brotherhood Lodge, Awo Ologboni Ilu Indian, yatọ patapata si Ẹgbẹ ti a ṣe abere yi ati pe ko si ohun kankan ti o pa Ẹgbẹ yi eyiti a npe ni The White Brotherhood Lodge pọ pẹlu Ẹgbẹ ti o polowo ara rẹ sinu Iwe Irohin ti 26th. November, 1951.

A ṣe ikede ati ikilọ fun Awọn Ọrẹ. Onibara ati Awọn Ọmọ Awo pe a ko ni ibi meji ju 29, Ramos Street, Idi-Oro Yaba Nigeria lọ, ati pe ẹnikẹni ti o ba fi iwe rẹ ranṣẹ tabi ṣi iwe rẹ fi ranṣẹ si ibomi eleyi ko kan wa rara o.

THE OLUWO
29, Ramos Street, Idi-Oro, YABA NIGERIA

OWE :— BI NGO TI SE INKAN MI NIYI NI AṢI WUKE FI ṢEGUN OLOGBON ...

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

IDAHUN SI IBERE LADIPO OJO

Nipa ibere Ogbeni Joseph Ladipo Ojo ti o bere ninu Iwe Irohin Yoruba ti 2.7:51, pe bawo ni Oke-Sioni tin?

Idahun kini si ibere na nipe Oke Sioni ti Dafidi Oba wi je ibudo Olorun tabi ilu mimo, ko si ibiti a le fi we e ni aiye yi mo Akanda ri Olorun da oke na, gege bi eri apejuwe re ti o ori ka ninu Orin Dafidi ori 133 ese 3 ori 99 ese 2 ori 110 ese 2 ori 135 ese 21 ori 2 ese 6 ati Isaiah ori 33 ese 20, ori 12 ese 6, ori 14 ese 32.

Emi ni
E. O. Martins
(Toju-iwa-re)

120 Clifford St
YABA

IDAHUN SI IBERE OGBENI G A ADELEYE

Nipa ibere Ogbeni G. A. Adeleye Gedwill, Idowa-ijebu ti o jade ni 2:7:51 pe kinise ti awon onigbagbo fi ngbe oku lo si Sosi ki nwon to gbe e sin ati okeji ni pe kinise ti Jesu fi gegun fun igi opoto

Idahun.- Ki ise gbogbo onigbagbo lo ngbe oku won lo si Sosi nitori ko si eri fun eo ninu Bibeli, Gegebi bi awon Imale ti ni eya egbe esin bi Alalukurani, Olumodin, Asarudini ati bebe lo bena ni awon Ijo onigbagbo wa orisirisi.

Idahun si ibere keji-: Jesu kan fi ise iyanu han lara igi opoto na ni, nitori ki Jesu to de idi igi opoto na ni o ti mo pe ko si eso lori re sugbon ki awon omo ehin re le ni igbagbo pe Jesu ni ase lori ohun gbogbo ni o se lo ase iru eyi lori igi opoto na. Wo Marku 11 13-14 ati 20 - 24.

Emi ni
E O Martins
(Toju iwo re)

120 Clifford St,
YABA,

Akiyesi:- Idahun ti Ogbeni Peter A Oyinloye ti Irere dahun si ibere mejeji yi fere ba ti Ogbeni E O Martin dogba ni a ko se tun te idahun tire na jade mo.

OLOTU

## TI EDA NI IMO




Ona ti o le fi ni imo, Ti o le fi mo gbogbo ohun ijinle nipa eda eyiti yio ma a se anfani fun e lojojumo. Ti wa a fi ni ilera, oro, inudidun, orire, ati bee lo. Ki o le mo aipa ofin eda, wa wo "EGBE ANCIENT KURAJEEH WHITE BROTHERHOOD LODGE" a fi ese re le ona taara na. A ni orisirisi iwe adura ati ti imo ijinl, nipa emi, e kowe bere alaye kikun ki e si fi sisi (6d) si i si:-

The Ancient Kurajeen White Brotherhood Lodge
528 CLIFFORD STREET, EBUTE-METTA, LAGOS.

E MAA KA IWE Irohin Yoruba NIGBA-GBOGBO

AMODI IMU TI LO



MENTHOLATUM



Ki amodi imu ba le tete lo, lo "Mentholatum" pelu iyanu ni igbogi fifa-si imu yi fi tete ayara sise. Esekese ti o ba ti lo o ni wa ti ri i pe irorun ni gbogbo idoti imu o ti bere si jade lesekese. Orun "Mentholatum" a tete fun e ni aye a ti ma a mi dada. Ki o si tun fi pa efun ati aiya fererfe. Eyi na a si tun ma a mu ki gbogbo iwojopo ailera lo kiakia. Tete lo ra ide tabi agolo "Mentholatum" kan loni,

Bere fun "Mentholatum" gan an. Ebiti o je ne awon Mentholatum Co. L'td (Est 1889) Slough England nikan ni nwon se e.

No 454

## Government Notice

With reference to the recent publication under the Public Collections (Regulation) Ordinance, 1947, of the accounts of the African Academy of Arts and Research, it has been decided that no facilities can be afforded by Government to any student, other than those already receiving education in North America, who is sponsored by the Academy.

### IKORE AWON OMODE

ABALABI— Ikore yi dun pupo ti a ko le fenu rohin re tan, irohin ko to afojuba. Awon Olukọ je metala, awon omo ile-iwe je 324. Awon Ero Ijo je 713 lokunrin lobinrin.

Alufa J A Akinwande ni alakoso isin na, eniti o wasu ni Ogbeni T S O Dohensi alabojuto African Church Schools ti agbe Agege. O yan iwasu re lati inu awon iwe wonyi:- Ex Ori 12 ese 25-27, ati Luku 2, 49 Owo ti a kojo je £68.8-8d.

Ogbeni A L Olofinjana se bebe nipa fifun awon e ia Ijo ni ecla Ile wa ti o gbadun, pelu awon egbe akorin ti o ko won,

Ki Olorun je ki a se opo re, ki O si da awaye eniyan wa, ase o.

